# AISÀN ATI IYIRIWÒ HẸSEKIAH

### 2 Awọn Ọba 20:1-18; 2 Kronika 32:26, 31-33

### ẸKỌ 345 --- FUN AGBA

**AKỌSORI: "Ọlọrun, wadi mi, ki o si mọ̀ aiya mi: dán mi wò, ki o si mọ̀ iro-inu mi: Ki o si wò bi ipa-ọna buburu kan ba wà ninu mi, ki o si fi ẹsẹ mi le ọ̀na ainipẹkun" (Orin Dafidi 139:23, 24).**

**I Aisàn Hẹsekiah ni Akoko Idaamu Juda**

1 Ẹgbẹ ogun Sennakeribu daya fo Jerusalẹmu, 2 Awọn Ọba 20:6; 18:17

2 Isaiah sọ fun Hẹsekiah pe yoo kú ninu aisàn rẹ̀, 2 Awọn Ọba 20:1; Isaiah 38:1

3 Hẹsekiah sọkun niwaju Oluwa, 2 Awọn Ọba 20:2, 3

**II Ọlọrun Onișẹ-Iyanu**

1 Ọlọrun rán Isaiah padà ni idahun si adura, 2 Awọn Ọba 20:4-6

2 A wo Hẹsekiah sàn, 2 Awọn Ọba 20:7; Jakọbu 5:14, 15; Ẹksodu 15:26

3 Ọlọrun rán àmì kan, 2 Awọn Ọba 20:8-11; Marku 16:17, 18

**III Iyiriwo Hẹsekiah**

1 Hẹsekiah gba alejo lati Babiloni wá, 2 Awọn Ọba 20:12, 13; 2 Kronika 32:31

2 Ọkàn Hẹsekiah gbega, 2 Kronika 32:25, 26; Orin Dafidi 101:5; Owe 6:17

3 Isaiah bá Hẹsekiah wi, o si sọ nipa akoko igbekun ni ilẹ Babiloni, 2 Awọn Ọba 20:14-18

4 Hẹsekiah kú, 2 Kronika 32:32, 33

## ALAYE

### Agbara ninu Ailera

A fi ẹgún kan sara Paulu nitori ki o ma baa gberaga. O bẹ Oluwa ni ẹrinmẹta ọtọọtọ ki a mu un kuro, șugbọn ohun ti o gbọ ni eyi: "Ore-ọfẹ mi to fun ọ: nitoripe a sọ agbara mi di pipé ninu ailera" (2 Kọrinti 12:9). O daju pe ni akoko idanwo ati aisàn – nigba ti a ba wà ninu ailera -- igbẹkẹle wa ninu Ọlọrun maa n pọ̀ jọjọ, agbára Ọlọrun yoo si fara hàn.

### Iná Atunnișe

Hẹsekiah ọba jẹ́ ẹni iwa-bi-Ọlọrun, ẹni ti o fi gbogbo ọkàn rẹ̀ sin Ọlọrun; șibẹ ọ̀pọlọpọ idanwo ni o doju kọ ọ lati yiri rẹ̀ wò ati lati rẹ̀ ẹ́ silẹ. Sennakeribu dide si i pẹlu gbogbo ogun Assiria; iparun si rọ̀ dẹdẹ lori ijọba Juda. Ki Hẹsekiah baa le doju kọ idanwo yii o mu ara rẹ̀ le ninu Oluwa. Lati mu ki ọran naa tubọ le sii, akoko ti a dó ti Hẹsekiah ni o șaisan titi de oju ikú. O dabi ẹni pe, lati fi kun idaamu rẹ̀, a tun rán Wolii Isaiah lati sọ fun ọba ẹni ọdun mọkandinlogoji yii pe ki o pa ilẹ ile rẹ̀ mọ́ nitori ti oun yoo kú.

Wo bi ọjọ naa yoo ti jẹ ọjọ ibanujẹ to fun ọba yii nigba ti Isaiah jișẹ ikú fun un, ti o si fi i silẹ bẹẹ! Yoo dabi ẹni pe gbogbo ogun ọrun apaadi ni o dide si i, ọrun pẹlu si dabi idẹ loke ori rẹ̀. Hẹsekiah yi oju rẹ̀ si ogiri, ninu ibanujẹ ọkàn rẹ̀, o sọkun kikorò. Wo bi idahun ti o lagbara ti de kánkan lati ọdọ Ọlọrun nigba ti Ọlọrun ri i pe iná ipọnju fẹrẹ bori iranșẹ Rẹ̀. O fara jọ igba ti Abrahamu gbé ọ̀bẹ soke lati fi ọmọ rẹ̀ kan șoșo ọ̀rubọ, ti angẹli Oluwa si kọ si i lati Ọrun wa ti o si și i lọwọ. Ki Ọlọrun ma șai jẹ ki o di mimọ̀ fun gbogbo awọn ọmọ Ọlọrun pe Ẹni ti n tun Lefi șe mọ wura Rẹ̀, Oun ki yoo si jẹ ki iná ki o gbona ju bi o ti yẹ lati tún awọn ọmọ Rẹ̀ șe!

### Ișẹ-ami ati Ișẹ-iyanu

Ișẹ Oluwa ti jẹ iyanu to! Iranwọ Rẹ̀ si ti tobi to nigba ti O ba na ọwọ Rẹ̀ jade! Pẹlu ami ati ișẹ-iyanu, O sọ ara Rẹ̀ di mimọ̀ fun Hẹsekiah. Angẹli ikú ré ọba Juda kọja, o si pa awọn ọmọ-ogun Assiria, o fi Sennakeribu silẹ lati pada si Ninefe pẹlu ifajuro ati itiju, bi awọn wundia Sioni ti n mi ori wọn, ti wọn si n fi rẹrin ẹlẹya.

Ki i șe awọn wọnyi nikan ni ohun iyanu ti o șelẹ ni ọjọ ma-ni-gbagbe yii nitori pe Ọlọrun rán Isaiah pada lati sọ fun Hẹsekiah pe Oun yoo wò ó sàn, Oun yoo si fi ọdún mẹẹdogun kun ọjọ aye rẹ̀.

Lati fi idi rẹ̀ mulẹ pe iṣẹ naa ti ọdọ Ọlọrun wá, Isaiah ké pe Oluwa, Ọlọrun si mu ki oorun pada sẹyin ni ogoji iṣẹju, yoo si dabi ẹni pe ni ṣe ni agogo oòrun Ahasi n ṣiṣẹ segesege nigba ti ojiji pada sẹyin ni iṣisẹ mẹwaa. Wo iru idagiri ti yoo dá silẹ laarin awọn eniyan ti o wà ninu ayé lati ri i pe oorun pada sẹyin ni oju ọrun! Bi awọn alaigbagbọ́ ba fẹ wọn le maa fi ohun ti o ṣẹlẹ yii ṣẹfẹ: ṣugbọn Ọlọrun Hẹsekiah ni Ọlọrun ti O dá oorun, ayé ati ofurufu; Oun ni O n mu ki ohun gbogbo ti o wà ninu agbaye ki o maa ṣiṣẹ letoleto: bi O ba si fẹ O le yi eto yii pada si idaamú awọn ti kò gbagbọ́.

**Iyin**

Wo bi ayọ naa yoo ti pọ to ati bi ile Oluwa yoo ti maa ho fun orin ayọ ni ọjọ kẹta nigba ti Hẹsekiah wá lati fi ọpẹ fun Ọlọrun fun idasilẹ ati ọdun mẹẹdogun ti a fi kún ọjọ ayé rẹ! "Iboji kò le yin ọ, iku kò le fiyin fun ọ: awọn ti o sọkalẹ lọ sinu ihò kò le ni irèti otitọ rẹ. Alãye, alãye, on ni yio yin ọ, bi mo ti nṣe loni yi." Ọrọ wọnyi ni o ti ẹnu ọba jade. O gba gbogbo ọ̀dẹ̀dẹ̀ kan, gbohungbohun si gbe e jakejado agbala tẹmpili.

**Iwosan**

Lati gbadura si Oluwa fun iwosan gẹgẹ bi Hẹsekiah ti ṣe ki i ṣe ohun ajeji si awọn ọmọ Ọlọrun. Oluwa ti ṣe ileri pe, "Emi li OLUWA ti o mu ọ lara dá" (Ẹksodu 15:26). Ninu Ọrọ Rẹ̀, a gba awọn ti a n pọ́n loju niyanju lati gbadura, a si ke si awọn alaisan lati pe "awọn àgba ijọ, ki nwọn si gbadura sori rẹ̀, ki nwọn fi oróro kùn u li orukọ Oluwa: Adura igbagbọ́ yio si gbà alaisan na là, Oluwa yio si gbé e dide" (Jakọbu 5:14, 15). Agbara Rẹ̀ lati wosàn kò pamọ titi di oni-oloni fun awọn wọnni ti o ba gbẹkẹ wọn le E.

A fi awọn ti o gbẹkẹ le apá ẹran-ara ti ọkàn wọn si ṣi kuro lọdọ Ọlọrun gegun. Inu Ọlọrun kò dun si Asa ẹni ti "kò wá OLUWA, bikòṣe awọn oniṣegun" (2 Kronika 16:12). Asa kò ri iwosan, o si kú; ṣugbọn Hẹsekiah gbadura o si yè. Awọn ẹlomiran le maa tọka pe eso ọpọtọ ti Isaiah sọ fun Hẹsekiah lati fi ṣan oowo naa jẹ́ apẹẹrẹ lilo egbogi. Kò ṣe e ṣe fun eso ọpọtọ lati wo oowo naa sàn gẹgẹ bi kò ti ṣe e ṣe fun omi Jọrdani lati wo arun ẹ̀tẹ sàn. Amọ̀ ti Jesu lò lati fi pa oju ọkunrin afọju nì ki i ṣe oogun fun oju fifọ gẹgẹ bi ororo ti awọn alàgba ijọ n ta sori awọn alaisan ki i ṣe oogun iwosan. Igbọran si aṣẹ Ọlọrun ati igbagbọ́ ninu Ọlọrun ni o n jẹ ki awọn alaisan ri iwosan gbà; aajo tabi iranlọwọ ẹran-ara kò ni nnkankan ṣe lati mu ipinnu Rẹ̀ ṣẹ. Jẹ ki awọn ti n sin Ọlọrun ki o fi tọkàntọkàn gbe ẹkẹ wọn le "Ẹniti o si tán gbogbo àrun rẹ" (Orin Dafidi 103:3).

**Igberaga**

"Ṣugbọn Hẹsekiah kò si tun pada san gẹgẹ bi ore ti a ṣe fun u: nitoriti ọkàn rẹ̀ gbega" (2 Kronika 32:25). Ara ti le, ihalẹ awọn Assiria ti di asán, ọrọ̀ ati ọlá si de fun un, o yẹ ki Hẹsekiah ki o rìn ni irẹlẹ niwaju Ẹlẹda rẹ ti o ti ṣe ohun iyanu fun un. Ṣugbọn nigba ti awọn ikọ̀ mú ọrẹ ti Babiloni wá fun un, eyi jẹ́ idẹkùn fun un. Pẹlu igberaga ọkàn o fi gbogbo iṣura rẹ̀ hàn fun wọn. Lẹkan si i Ọlọrun rán Wolii Isaiah si Hẹsekiah, ṣugbọn nisisiyii, lati ba a wi fun iwa aṣiwere rẹ̀.

"Igberaga ni iṣaju iparun, agidi ọkàn ni iṣaju iṣubu" (Owe 16:18). Ohun gbogbo ti Hẹsekiah ati Juda n fi hàn pẹlu igberaga ni a o gba lọ kuro lọwọ wọn. Gbogbo awọn iṣura ti wọn fi n ṣe féfé ni yoo bọ́ si ọwọ́ awọn ara Babeli niwaju ẹni ti wọn ti n fẹ̀ soke. Ki Ọlọrun ki o ran gbogbo wa lọwọ lati mọ̀ pe igberaga jẹ ohun irira niwaju Ọlọrun. "Okú eṣinṣin o mu ororo-ikunra alapolu bajẹ ki o ma run õrùn buburu: bẹ̃ni wère diẹ wuwo jù ọgbọ́n ati ọlá lọ" (Oniwasu 10:1).

**Irẹlẹ**

Hẹsekiah gba ibawi yii lati ọdọ Oluwa, gẹgẹ bi ẹni nla, o rẹ ara rẹ̀ silẹ; Ọlọrun si sun ọjọ ikolọ Juda siwaju ti kò fi ṣẹlẹ ni ọjọ Hẹsekiah. Nitootọ Ọlọrun juba awọn onirẹlẹ o si "gbà iru awọn ti iṣe onirora ọkàn là" (Orin Dafidi 34:18). Ọlọrun boju wo ẹni bi Ahabu apaniyan, nigba ti o rẹ ara rẹ̀ silẹ nipa ibawi Elijah; O si gbọ́ adura Manasse ti o fi ẹjẹ alaiṣẹ kún Jerusalẹmu nitori ti o rẹ ara rẹ̀ silẹ gidigidi. Ọlọrun maa n na ọwọ aanu Rẹ̀ si awọn ti o ba rẹ ara wọn silẹ ti o si mọ ara wọn ni ẹlẹbi niwaju Rẹ̀. "Ẹ rẹ ara nyin silẹ niwaju Oluwa, on yio si gbé nyin ga" (Jakọbu 4:10). Tabi iwọ ti tobi ju loju ara rẹ lati rẹ ara rẹ silẹ?

## AWỌN IBEERE

1 Ka itàn igbesi-ayé Hẹsekiah lẹsẹẹsẹ ki o si sọ bi o ṣe mọ̀ pé aisàn dé ba a ni akoko ti Sennakeribu gbogun ti ilẹ Juda.

2 Sọ diẹ ninu awọn ohun ti Hẹsekiah ṣe lakoko ijọba rẹ ki o to ṣaisàn.

3 Ẹni ọdun meloo ni Hesekiah nigba ti aisan kọ lu u?

4 Bawo ni o ti pẹ to ki Ọlọrun to gbọ́ adura rẹ fun iwosan?

5 Tọka si diẹ ninu awọn ẹsẹ Ọrọ Ọlọrun ti o mu ki a gbẹkẹ le Ọlọrun fun iwosàn.

6 Bawo ni a ṣe mọ̀ pé ogoji iṣẹju ni iṣisẹ mẹwaa ninu agogo-oorun Ahasi bọ́ si?

7 Iṣẹ wo ni eso ọpọtọ ṣe ninu iwosan Hẹsekiah?

8 Tọka si awọn asọtẹlẹ miiran nipa ikolẹru lọ si ilẹ Babiloni.

9 Ki ni kò jẹ ki ibinu Ọlọrun wa sori Jerusalẹmu ni akoko ijọba Hẹsekiah?